# ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 907 LAGOS SATURDAY FEB 8 — FEB 14 1964 KOBO MEJI (1D)


### ONISEMO PADE AGBAKO!

# Ojowubinrin P'oko Re Sorun Alakeji, O Koo Ni Woro Abe

EKO- Gbogbo awọn obinrin ni nwọn ma njowu, sugbọn ti ẹnikan ju ẹnikan lọ ni ọ r ọ ojowu obinrin kan, ( ti a fi orukọ bo laşiri ) ti o pa ọkọ rẹ ti nwọn npe ni Onisẹmọ de ọrun ni alẹ ijẹta n i t o r i p e o b ẹdọmodebinrin kan ti o nyan l'ale ni inu iyara lọdọ rẹ.


(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## Iyori Idibo Agbede Meji Iwo Orun

Awọn ọmọ ẹgbẹ NCNC ko adọta (50).
Awọn ọmọ egbẹ oşelu tuntun MDF ni mewa (10)
Awọn ẹgbẹ Ọlọpa pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ BODA-KOWA nwọn ko ri nkankan ko rara.

# Awọn Loya Tuntun Miran Yege Nilu Oyinbo

LONDON— A ti irohin gba ni oru ana lati ilu Oyinbo ni London wipe ogunlọgọ awọn ọmọ wa ti o nko işẹ agbẹjọro (lọya) ni nwọn yege ninu idanwo ti nwọn şe fun wọn laipẹ yi, ọpọlọpọ nwọn si ti npalẹmọ lati wa si ile lati wa bẹrẹ isẹ.

Awọn agbajọ ẹgbẹ mẹta ni nwọn jẹ pataki ti nwọn laşẹ lati fun enia ni iwe ẹri wipe o yege ninu işẹ agbẹjọro (lọya), orukọ awọn agbajọ ẹgbẹ mẹta na ni Lincolns. Middle Temple ati Inner; Temple awọn mẹtẹt na ni nwọn fun awọnọmọ wa ti o yege işẹ lọya lọdọ awọn ni iwe ẹri.

Orukọ awọn ti Lincolns In fun ni iwe pe nwọn yege lọdọ awọn ni:
Afolabi Olusanya Jaiyesimi, Ikorodu: Emmanuel Adebayo Odunaike, Ikenne Ijẹbu-Remo: Joseph Chukwudebelu Njelita, Onitsha: Alabi Ajose, Yaba, Lagos: Sani Salith Aikawa, Kano: Abubakar Bashir


(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## AYILUKA NI:

### Ọro Gomina Tuntun Dun Awon Ara Ibinni

Mo ni ibiti ẹlẹkun gbe nsọkun ni awọn alayọ nyọ mo gbọ wipe awọn ara ilu Ibinni ti mu aşọ ati ilẹkẹ ti nwọn yio lo lati fi ba Ọba Akenzua yọ ayọ ti Gomina ti a fi ngbọ wipe nwọn fẹ fi jẹ, ki a to tun gbọ wipe Oloye Samuẹli Jereton Mariere ọmọ ilu awọn Isobo (Urhobo) ni nwọn gbe oye Gomina Ijọba tun un na fun.

Gomina Ọlọla Samuẹli Jereton Mariere, mo ki ọ pupọ, eku orire! DO, OBOADORI, ADORI NAGA! GA ade ti awọn Isobo fi nke ara wọn ni mo fọ yẹn; emi na ti ba wọn gbe ni Warri ri, ilu wọn ti o wa ni ori omi ni kan ni nko le lọ nitoripe nko le ba wọn mu oti ogogoro nitoripe on ni nwọn fi nşe omi mu ni agbegbe Warri lọhun. Gomina Mariere oye yi a mọ ori o.

### Ibadan Le Mo

Şe mo sọ fun ẹnyin okawe mi ni ọsẹ ti o kọja wipe awọn ti nwọn ko ba mọ idi ọrọ ni yio ma ba wọn da sii awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ Ibadan. Ọrọ wọn şoro lati da si. Bi awọn ara Ibadan ni nwọn nlo ipo fun awọn ọmọ egbẹ Alakukọ (NCNC) ni, bi awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni nwọn si nlo Ibadan fun awọn ọmọ Ibadan ni, ao ma gbọ gbogbo bi nwọn ba ti şe ara wọn si ni ọtunla sugbọn mo gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ na ti yọ akọwe wọn kan, Lọye R. Akinjide, ọmọ Ibadan, wipe ki o fi işẹ ẹgbẹ awọn silẹ fun igba diẹ: Ki a ma şe tan ara wa jẹ nwọn fi Ọgbọn yọ Akinjide n yẹn.

### O Ko Mo Leyipo

Ọrọ ija wọn na ko ti le dun lẹnu emi Ayiluka, mo fẹ ki ẹ fojt yin silẹ diẹ, ki ẹ ma wo gudugbẹ ti o fẹ ja silẹ larin awọn ara Ibadan ati awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ Ipinlẹ Iwọ-Orun.

Awẹ ngbo mi, iyoku di ọsẹ ti mbọ ki nto fọ nkan loju fun yin nipa awọn oşelu wa.

# First Luboil Plant In West Africa Opened

LAGOS—West Africa's first Lubricating Oil Blending Plant built by the Shell Company of Nigeria Limited at Apapa, Lagos, was officially opened by the Fedral Minister of Mines and Power, Alhaji the Hon. Yusuff Maitama Sule, M. P., recently.

The plant cost £210 000, and is providing Nigeria with its first supplies of locally finished lubricating oils.

Before the plant began production, Shell imported all its finished lubricating oils. Now the Company imports only basic materials, and blends to produce the main grades of lubricating oils needed by Nigeria's fastt growing industry and also for export to neibouhring countries.

The plant will produce up to £10,000 tons of lubricating oils a year from feedstocks dischaged from ocean thankers at the Apapa jetty through a specially fabricated pipeline half a mile long, into eight main storage thanks.

A Nigerian, Mr. N.I. Udono who, in 1963 was sent to Mombassa in Kenya study the detailed operation of a similar plant built by Shell in that country, is in charge.

It was stated by the General Manager of the Company, Mr A D MacPherson during the opening ceremony that the whole installation at Apapa represents an investment of £1,250,000 itself. In addition, there are bulk depots at Port-Harcourt, Onitsha, Kaduna, Jos, and Kano, but taking into account our transport fleet' aviation facilities, stocks etc., the overall fixed capital invested by The Shell Company of Nigeria is £5,250,000. All this is required to ensure that the customer gets his requirements at the right place, at the right time and in first class condition.



Alhaji Yusufu Maitama Sule,
Minister of Mines & Power

# Nigeria's Educational Links With Britain

LONDON - Ways of increasing the flow of Nigerian postgraduate students to Britain are being discussed this week by the Agent General in Britain for Eastern Nigeria, Mr. Akpan Ekukinam Bassey, during a twelve-day tour of universities in Northern England and the Midlands.

Mr. Bassey; who started his tour on Sunday last, said at Leeds University, on Wednesday, that although the number of Nigerian universities was increasing, Nigeria still wanted to preserve education links with Britain.

"As the flow of undergraduate students to Britain declines, we want to see the number of our postgraduates studying at British universities increasing", he said.

Make it a Successful SEASON
with Mercedes-Benz TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

OLOFINTOTO NI:

# Jagunjagnn Ju Jagun-jagun Lo (2)

Eleyi ni yio di iwe keji ti emi Oofintoto yio ko ni akole lori awon soja jagunjagun ilu m e t a ni apa Ila orun Afirika ti nwon şeşẹ gba ominira ti awọn şọja ilu wọn ni ki nwọn fo ki nwọn niso, ti nwọn ni bi nwọn ko ba wo ti awọn şe, awọn y i o d a gbogbo ẹ ru patapata.

## Alamulegbe

Gẹgẹbi m o t i s ọ f u n ẹnyin ọkawe mi ninu iwe yi ni ọsẹ t i o kọja wipe alamulegbe n i a w ọ n ilu mẹtẹta, Uganda, K e n y a ati Tanganyika ti a w ọ n ọmọ ogun wọn d a ijangbọn silẹ fun awọn a r a ilu wọn yi. Erekusu ni ilu Zanzibar ti ko ba şe ikẹrin wọn, ti awọn janduku ibẹ le ọba wọn wọ igbe.

Mo g b ọ wipe nkan ti a npe ni OMINIRA IJỌBA ko ye awọn ỌMỌ ILU TANGANYIKA TI NWỌN GBA IŞẸ ŞỌJA RARA; ero ọkan wọn ni wipe ti Ijọba awọn ba ti gba ominira f u n awọn, gbogbo nkan lati yi pada si rere, a w ọ n si ni lati ma mu, k i awọn m a yọ niuu owo, sugbọn lati bi ọdun kẹta ti Gẹsi ti gbe Ijọba awọn le awọn lọwọ nkan ko yi pada nilu.

## Ijoba Onigbese

Nitotọ owo ko si lọwọ Ijọba wọn, ogoji ọ d u n gbako ni awọn Ijọba Gẹşi fi ba wọn şe eto ilu Tanganyika yi ki nwọn to gbe fun awọn ọmọ onilẹ lọwọ Ọgbeni Julius Nyerere tişe Olotu ilu na fi igbakan to awọn ara i l u Gẹsi lọ wipe ki nwọn fi owo ran Ijọba awọn lọwọ.

Iwọnba ti a p a a w ọ n Gẹsi ran nwọn şe fun wọn sugbọn awọ na ko ka oju iju, awọn alamojuto ilu na paapa si tẹsẹ wọn bọ sokoto wa ọna t i ilu w ọ n yio fi r i ilọsiwaju n i p a nkan aje.

## Ero Kukuru

Ero wipe bi awọn ba le le awọn şọja oyinbo ti o jẹ ọga awọn lọ, ki awọn si bọ sipo wọn, a wọn a ma ri owo -oşu gba daradara ni o wa lọkan awọn şọja ilu Tanganyika Uganda ati Kenya (ti ko ti pe ọdun kan ti awọn yẹn gba ominira ilu wọn) ti nwọn fi faake kọri wipe ki awọn kuku fọ gbogbo

Awọn ara ilu Zanzibar ni Ọba ti awọn pẹlu awọn Olowo ẹgbẹ rẹ, awọn Larubawa ti nwọn ti Mẹka wa mulẹ nibẹ ni nwọn fẹ sọ awọn dẹru, idi rẹ niyi ti awọn şọja wọn ba fi yọ kunmọ pẹlu ibọn lati fi ija ogun - adaja yanju ebi pẹlu işẹ ti o nşẹ wọn,

## Gesi Okunrin L'ada

Olotu ilu Kẹnya, Ọgbẹni Jomọ Kẹnyatta ti mọ iru rukerudo ti ọrọ awọn şọja na le dasilẹ ki o to ti waya bẹ awọn Olotu Ijọba Gẹsi wipe ki nwọn ba on wa awọn şọja jagunjagun ki o wa gba awọn lọwọ awọn şọja ọlọtẹ ilu awọn.

Jọ ọ Kẹnyatta nikan kọ ni o tẹ waya si ilu Gẹsi fun awọn şọja, Dokita Obote ti Uganda ati Nyerere ti Tanganyika pẹlu bẹ awọn alaşẹ ilu Gẹsi wipe ki awọn şọja wọn ran awọn lọwọ. Gbara ti awọn şọja na ti de awọn ilu mẹtẹta wonyi ni nwọn ti fi han wipe JAGUNJAGUN KAN JU JAGUNJAGUN LỌ. Gbogbo awọn şọja ilu na ni nwọn ti ko ni igbekun lọ fun awọn alaşẹ ilu wọn.

## Idi Re O

Şe ẹnyin na wa ri wipe awọn jagunjagun kan ju jagunjagun kan lọ, yẹyẹ ni a mba kiri ti a nsọ wipe ko si nkan ti a ko le şe nibiti awọn Gẹsi gbe wa ?

Ọrọ ọpọ awọn Oyinbo oşelu, ni gbogbo igba ti awa enia d u d u nsa fun ominira lati d a duro, ni nwọn nsọ wipe a ko le şe re a o ma to ominira wa lati fi ni ara wa lọra ri.

Nipa gbogbo nkan ti a nri ti o nja lalẹ ni aron wa nilu awa enia-dudu yẹ ki a mo wipe o dabi ẹni wipe otito ọrọ ni ọrọ awọn Oyinbo oşelu yi.

Lori ọrọ awọn şọja ilu awọn ara wa ni Tanganyika, Kenya ati Uganda ti mo nsọ ọ r ọ w ọ n y i, awọn idi mji ni a w ọ n olotu ilu Tanganyika ti yọ lẹnu işẹ wipe ki oluku luku wọn ma lọ sile wọn ko si işẹ şọja mọ nitoripe nwọn le pe ọta wọlu fun awọn.



# ELETI-OFE

(ANJU WỌN KO ŞE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAME
28, Kusoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
B. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 907 SATURDAY Feb, 8 - Feb, 14 1964.


## ORO OLOTU:

# Awon Ala-ilojuti

Ọrọ ti Olotu wa vio fi gba ẹnyin ọ'kawe wa ni iyanju ninu ọse yi ỌRỌ AWỌN AWO NI o ye, ko ye AWỌN ỌGBẸRI NI ọrọ na fẹ bọ si, bẹ aabo ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi bi o ba de inu rẹ a di odidi.

Bi a ba wipe ki a fọrọ mọlẹ ni ti ododo o dabi ẹni wipe iru yi ni awọn oşelu ti ki ronu gbe wa pupọ ni ọdọ wa nibi ni awọn oşelu kan ti nti ijoko ẹgbẹ kan bọ si ẹgbẹ oşelu kan ni ile igbimọ lai naani awọn ti nwọn ran an lọ si igbimọ asofin na. Kini faa ? Ole, ọkanjua ati iwa tanjẹmum .

Nitotọ, tani le mu awọn alailojuti ? ko si iwa ti awọn alailojuti ko le hu. Awọn agbalagba ti sọ wipe onitiju ko lojuti le leşo gongo şoja ki o şu sibẹ papa-rẹ nitori arun alailojuti ti o mba a ja. Arun alailojuti yi bi o ti wa ni iarin ọkunrin ni o tun wa larin awọn obinrin pẹlu, sugbọn ti awọn oşelu wa ni o buru ju.

Oni wa gbọ wipe ẹnikan binu kuro ninu ẹgbẹ oşelu yi, ọla wa tun gbọ wipe ọkan ti tun ja awọn ti o ... wọ ile igbimọ na silẹ lọ si ọdọ awọn ẹgbẹ oşelu kan hoya o le ri ibikan ba wọ ọ nibẹ. A dẹhinwa adẹhinbọ omulẹmofo ni gbogbo rẹ mbọ si, oju a wa ma ti awọn baba oşelu alailojuti, awọn ọmọ ẹgbẹ kan ko ni wa gba a mọ.

# Iwe Si Olotu

# Se Aiye Oti Niyi?

Ẹ jọwọ Olotu, laipẹ yi ni mo ka iwe kan ti AYILUKA kọ nipa ile ọti-lile ti nwọn fẹ ma pọn fun wa nilu Nigeria, ti nwọn nkọ si Apapa. Ọrọ na wa mu mi ronu pupọ wipe ki nle bere wipe şe aiye ọti ni gbogbo wa lọmọde lagba, ati lọkunrin ati lobinrin wa?

Ẹ jọwọ Olotu, laipẹ yi ni mo ka iwe kan ti AYILUKA kọ nipa ile ọti-lile ti nwọn fẹ ma pọn fun wa nilu Nigeria ti nwọn nkọ si Apapa. Ọrọ na wa mu mi ronu pupọ wipe ki nle bere wipe şe aiyi ọti ni gbogbo wa lomode lagba, lọkunrin ati lobinrin wa ?

Ni ilu awọn Hausa ti ẹ ni nwọn ki mu ọti, nibẹ. Ni Ẹnugun awọn Oyinbo ọlọti ti şe bebe si ibẹ ni Abeokuta, ilu Ẹgba, awọn onisowo kan ti tun şi ile ipọnti si Lafẹnwa nibẹ.

Bi awọn Oyinbo ajoji ba wa şi ile pọnti si fun wa o yẹ ki nwọn tun wo işẹ miran ti nwọn ri wipe o le mu nkan ilọsiwaju wa fun wa, ki nwọn daa silẹ.

Mo gba fun Ayiluka yin fun orişiri aşiri ọrọ gbogbo ti o ma ntu fun wa.

Abule Ijẹsha Emi ni,
Yaba A. Atanda

## Mo Gba Fun Ayiluka Eleti-Ofe

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati kan sara si Ayiluka Elei-Ọfẹ fun ọrọ rẹ ti ẹ ma ntẹ sinu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ni ọsẹsẹ. Ti mo ba ra iwe yin ọrọ Ayiluka na ni mo ma nwa kiri lati ka ki nle mọ bi nkan ti nlọ si larin awọn oşelu wa ni Ibadan, Enugu, Kaduna ati Eko.

Mo ro wipe ko si ibiti Ọgbẹni Ayiluka na ki de. Bi, o ti alọ sihin, ni o alọ sọhun ati ibi gbogbo gẹgẹbi ọrọ ori iwe rẹ na.

Ki a to şẹşẹ ka irohin agbejọro Ọba ti nwọn npe ni Nonyelu wipe obinu fişẹ silẹ ninu iwe irohin awọn Oloyinbo, Ayiluka ni o kọ kọ sọ irohin na sinu Eleti-Ọfẹ lati bi ọsẹ kẹta lọhun.

Mo gba fun Ayiluka yin, irohin mbẹ lọwọ rẹ.

Emi ni,
Ibadan S. Oyinlọla





E ma ka Iwe Iro-hin ELETI-OFE Losose Fun Iro-hin Aladun

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## O-SA-DE-BE

Emi Ayiluka ko mọ bi mba ti ki awọn ọrẹ mi ti awọn ṣẹṣẹ dibo ni agbede meji Iwọ Orun; bi ki nki nwọn ni EDE IBINI (TI A NPE NI ẸDO) ni bi ede awọn ti OLUKU mi, awọn Itṣẹkiri ni, bi ti awọn Isobo ni, bi ti awọn ara mi ni eti odo Ọya ni ilu Asaba ni; nko mọ eyiti mba fi ki nwọn ku orire ajabọ ti nwọn ja bọ lọwọ ajaga Saurdana ti nwọn sọ ada nu lọwọ Bello yi.

### Lati Owo Ayiluka

Ibo ti nwọn di na fa kiki, ṣe mo ti nsọ fun yin wipe lọjọ kan ọrẹ mi, Oloye Dennis Osadebay YIO DE IBẸ gẹgẹbi orukọ ti a ma npe Dennis nigbati a jọ nṣe ẹgbẹ Boy Scout pọ l'Eko ni ọdun 1929.

### Jambori 1929

Agbako amodi kan ti mo ko ni ko jẹki emi ati Ologbe Sumbọ Jibowu ba wọn lọ si ilu Oyinbo fun Jamboree ni ọdun 1929 ṣugbọn Dennis lọ pẹlu ọrẹ mi Ọnayẹmi ("JAMBOREE") onisowo ti o kọle si eti Ọja Jankara l Eko nisisiyi, pẹlu awọn miran ti ko si aye fun lati darukọ wọn sibi. Nigbati nwọn pada de nwọn rohin fun wa jọjọ.

Ẹnyin ọkawe mi, Oloye Osadebay ṣe ọmọlawabi pupọ; ti o ba ba a pade nigbati o nṣe iṣẹ akọwe-bode (Custum Officer) ni wa le jẹri si ọrọ mi yi, bẹ si ni burọda rẹ ti o wa nibi iṣẹ awọn akọwe awọnlẹ ni Enugu-Eko ni nwọn ti gbe e lọ sibẹ. Ṣe ẹnyin na wa mọ wipe mo mọ Oloye (tabi ọlọla ni ki npe e nitoripe ki ẹ to ma ka iwe irohin yi Dennis yio ti di Alakoso Ijọba Ipinlẹ agbedemeji Iwọ Orun NILU IBINU) Osadebay daradara.

### Aposulu Edopolo

Nibi ẹlẹkun nsọkun ni ulayọ nyọ; mo gbọ wipe nibiti awọn Ọmọlẹhin Oloye Osadebay gbe nyọ lori idibo ni awọn Ijọ Ṣọṣi kan ni Ioinni ngbawẹ agbayipe lati ọjọ ti nwọn ti ṣe ikede idibo fun gbogbo wa nile loko gbọ.

Ọrọ idibo yi awọn enia meji ni mo ba kanu nibẹ, awọn na ni Ẹni-ọwọ Aposulu Edokpoloati Ọgbẹni Kesington Mọmọh. Mo ti mọ ọrẹ mi Kesington ti pẹ nigbati o wa ni ile igbimọ ni Ibadan; ko si nkan ti o ko ba a nilu rẹ ju ẹgbẹ tuntun ti ko ni oriki ti o ṣeṣẹ bọ si lọ. Ṣe on na k ba ti duro lori ẹgbẹ Ọlọpẹ ti o ti mi wọn ṣẹ.

### Eyi Je

Emi ko le sọ bi Kesington ni o ko ba Apọsitulu, bi Apọsitulu Edopolo ni o ko ba Kesinton nitoripe ere asadojubolẹ ti moto ẹgbẹ ọṣelu wọn nna sa ko tẹ mi lọrun, inu mi ko si dun si jijona rara. Ọkan mi ko ntan mi jẹ; mo mọ daju wipe eleyi a kọ wọn lọgbọn wipe ọrọ ilu-ṣiṣe ọrọ tẹtẹ ni.

O dabi igbati awọn onitẹtẹ ko ba ma sọ wipe EYI JẸ! EYI KO JẸ!! Kinni ba Woli de ọdọ awọn onitẹtẹ oJeiu debi w... nwọn fi nyi i mọ ere lojude Ọba.

### Dafe Onikeja

Ko yọ o! ỌBỌHIAN Ede awọn ara wa, awọn ara IBINU ọmọ arokun tayo ni mo fi ki yin yi o. Ẹ jọwọ ẹnyin ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti ẹ bori idibo mo fi ori agbebọ adiẹ bẹ yin, ki ẹ jọwọ ki ẹ pe Ọgbẹni O.I. Dafe pada wa silẹ nitoripe eyiti o ṣe ninu papa ọkọ ofurufu ni Ikẹja yẹn to. Mo ro wipe lati igbati o ti ti ilu Oyinbo fun iṣẹ lọya ti o lọ kọ, o ti iye igba ti o fi wa ye won wo ni Abọh ilu rẹ. Ki on na fi oye DAFẸ ONIKẸJA silẹ fun awọn ẹlomiran emi Ayiluka paapa a a ki nilu Abọh ti o ba ti de ibẹ k o si ba mi wa ọpọlọpọ awọn ọmọge ti ma ba ṣere ki nto pada s'Eko.

(Wo iyoku loju ewe keje)

**Polowo Oja Re Sinu ELETI-OFE ti o kun fun ogbon ati Irohin aladun ni osose.**



## Baba Onimajiki Gbe:

# Ofin Tuntun Fun Awon Onibara

### Lati owo Malam Yakubu

Lati ọdun ti awọn Hausa onibara ti ngbe igba b... wọn kiri ilu Yoruba, nwọn ko ti pade agbako iru eyi awọn fẹ pada lọdọ awọn a ise ilu Eko ti nwọn s.ş; fẹ gbe OFIN MA S'AGBE jade fun awọn onibaara larin ilu Eko ati Ebute-Mẹtta mọ Yaba.

Mo gbọ wipe ọrọ ofin na fi ẹwọn oşu kan lọwọ fun awọn onibaara ti o ba lu ofin na tabi ki o fi pọn..n mẹwa sara tanran

Ẹ jẹki nla diẹ ninu awọn koko ti o wa ninu ofin tuntun na ... yin Ni ọna kinni awọn ... Kotu ijọba ni awọn lodi si wipe ki enia ma fi ijo-ijo ati orin kiko tabi ki o ma fọwa eru, bi ki a wipe a nwo ... tabi o-nmajiki tabi ki a ma wipe a nta ọja ti o le mu ... wa Olọwa rẹ lu igbadi ofin.

Ọlọpa le gba enia mu nita bi nwọn ba rii ti o npandan lati gbowo lọwọ awọn ti o nwo iran be tabi eniti o jẹki nwọn fi on se aworerin lati le rowo gba lọwọ awọn enia.

### Igba Baara

Awọn alasẹ ilu ni ẹnikẹni ti o ba t ojule kan de ojule kan, ti o nse agbe wipe ki nwọn ba on wa nkan lu ofin. Nwọn ni enia ko gbọdọ jẹ yo tan ki o ma fi ẹsẹ ti nduo un, tabi oju ti o fọ tabi ọwọ ti o rọ pẹlu dangborọku ẹsẹ tọrọ agbe kakiri.




Iwe Akoka Yoruba:

# Ile Ifi Ohun Atijo Pamo Si Ti Ile-Ife

### Lati owo Alufa Atilade

Iru awọn aworan wọnyi kanna fi igbe aiye ọkunrin han bi nwọn ti nşişẹ oko riro, ọpẹ kiko, işẹ agbẹdẹ, şşe ati işẹ ogun jija pẹlu awọn ohun ija wọn bi ọkọ ọfa ati ọrun, kumọ, ada ati ake.

O şe enia li anu lati şe akiyesi ọna ti nwọn nfi nmu awọn ẹru ni atijọ ati iru iwa ika ti a nhu si wọn. Nwọn a fi okun so ọwọ wọn mejeji pọ, nwọn a si fi okun miran ha wọn li ẹnu, eyiti nwọn yio tun so pọ ni ipakọ, ki ẹru na ma ba le sọrọ tabi ki o ke ara titi ti a o fi mu u de ibiti a ba nmu u lati ta a.

Irun tabi baba ni a fi ya aworan awọn Ọba ati ayaba. Awọn aworan wọnyi dara tobẹgẹ ti o fi jẹ pe bi ẹnikan ti o ... a ni akoko wọn ba pada wa si aiye loni, ko ni sọrọ fun lati mọ aworan Ọba tabi ti ayaba ti işẹ.

Nwọn şẹşẹ ri aworan ọba kan ni Ifẹ Ọba na wọ asọ oye bi gbogbo Ọba Ifẹ iti ma wọ asọ oye wọn pẹlu ade li ori rẹ, ilẹkẹ oye ni ọrun re ati ọpa oye ni ọwọ rẹ. Bi enia ba rii, yio wipe, "Baba, kabiyesi"!

Nipa işẹ ọna şişe bi işẹ ti awọn alagbẹdẹ, awọn Yoruba igba lailai ki işẹ ẹgbẹ awon Yoruba isisiyi. Ọpọlọpọ nkan ni a ni lati kọ lọdọ wọn.

Ni afikua gbogbo awọn nkan wọnyi, ohun kan tun şe ohun pataki ti a ni lati fi kun awọn ohun atijọ wọnyi bi o tilẹjẹ, ibomiran ni ohun na wa. Eyi yi ni ọpa ọranyan. Ọpa ... i jẹ ọpa okutẹ ti a ti ti a gbẹ ti a si kan iso mọ ọ lara. Ọpa na ga to ẹsẹ mẹwa tabi mejila, o si fẹ to ẹsẹ merin ni isalẹ. O wa bẹrẹ si ma dinku ni filẹ diẹdiẹ titi ti o fi pin loke.

Ni oju ọpa okuta yi ni a kan işo ọgọta o le kan si ni oro; bẹna ni a si kan ọgbọn işo o le meji ni poro meji ni ẹgbẹgbẹ ti poro ọlọgọta işo o le ọkan, wọn si tun kan l ti so ẹsẹ poro meji na pọ ni ẹba agbedemeji ti ọlọgọta işo o le ọkan. Lẹhin ti awọn işo wọnyi;

a tun kọ ọro meji si ara okuta na.

Awọn olutumọ sọ wipe, isọ ọgọta o le ọkan sọ iye ọdun ti Ọranyan gbe laiye ati pe o jẹ ẹni ọdun mejilelọgbọn nigbati o bere si ijọba.

Rev. Samuel Johnson, Onişe Itan Yoruba sọ itan kekere yi nipa Ọranyan ati ọpa ọpa okuta rẹ.

Ọranyan jẹ ọmọ ọmọ odudua, lara ẹniti orilẹ ede Yoruba ti şe ati ẹniti işe Ọba ti o tẹ Ile Ifẹ do. Ọranyan lo jọba tẹlẹ baba nla rẹ, Odudua ni Ile Ifẹ.

Ọranyan jẹ ologun enia. Adọjọ ọmọ ogun alagbara ni awọn ọmọ ogun ti nşu yi on nikan ka loju ogun. On ati awọn arakunrin rẹ meji pinnu lati pada lọ si Ila Orun nibiti Odudua baba nla wọn ti wa lati lọ gbẹsan lara awọn ti o le Odudua jade kuro ni ilu; şugbọn nigbati nwọn de ibi kan ti a npe ni Igangan, ija bẹ silẹ larin wọn nitori agbe ọti kan ti nwọn fẹ mu, nwọn si tuka.

(Iyoku di ọsẹ ti mbọ)

# Your Radio Next Week

## "HOW THE LAW WORKS"

Ignorance of the law is no excuse. Most people knew this, but they would be less likely to forget it, said Bill Everingham in a BBC African Service broadcast if they read a new book called "How the Law Works," by J. Ardle McArdle.

"All that examples of the application of law in this book are applicable to life in Africa," he said. "It relates the adventures of Kwame, the man who usually gets away with breaking the law, and of Danadamu, who commit so many breaches of the law that he should be in prison for the rest of his life. From the book you will learn the basic principles of law." However, readers would have to check on any local differences in the established law. The author had been very careful to explain that the law was not to be found in any simple book or code. It had been built up over the centuries by custom and usage and it was therefore impossible to give a detailed account of the different legal systems in all African countries.

"There are chapters in this book," continued Everingham, on so many aspects of law that it would be almost impossible for anyone not to find himself affected by at least one of them". Among them was the law about defamation, with which he was personally concerned in his BBC broadcat. If written words cause people to have a bad opinion of someone then he can win an ahtion for libel. As it happens I like this book, but I could defend what I say as fair comment because it is my opinion, which in this case I am allowed to broadcast freely.

Everingham ended his BBC broadcast by asking those listeners who thought they did not need any legal knowledge to test themselves with two of the problems he found in "How the Law Works."

"First, if your wife trades in the market under her own name, are you responsible for her debts? And second, do you need to put 'And Co. when you cross a cheque? The answer in each case was 'no'; a wife, if she worked on her own account, could not make her husband responsible for her business debts; and only the two lines were necessary when crossing a cheque. If you didn't get the correct answers, concluded Everingham, I suggest you buy the book. It may well save you a lot of money some day. At least you will earn a lot. I know I did."

## BBC NEXT WEEK

During the coming week programmes in the BBC African Service after the News at 12 o'clock (local time) on 17.81 and 21.615 megacycles in 16 and 13 metre bands, will be as follows:

| | |
|---|---|
| Sunday, February 9 | London Fanfare |
| Monday, February 10 | A book for today, Focus on Africa Around the town with Sherman Brown For you at home |
| Tuesday, February 11 | A book for today, Postmark Africa, African Mirror Calling Ghana |
| Wednesday, February 12 | A book for today Focus on Africa, African forum |
| Thursday, February 13 | A book for today Focus on Africa Discussion Balling Nigeria |
| Friday, February 14 | A book for today, Focus on Africa, New Horizons Writers Club |
| Saturday, February 15 | Showtime for Parents and Teachers Calling Sierra Leone |

## Medical Scholarships For Doctors

LONDON — A British firm is again offering six medical fellowships for one year's post-graduate study in Britain in a selected branch of medicine. The fellowships are offered under a scheme begun in 1961 by Smith and Nephew, manufacturers of medical products, to enable doctors from overseas to complete their studies in Britain. They are available to doctors in Commonwealth and developing countries who are studying for higher qualifications. The fellowships each worth £1,200, are awarded alternately for surgery and medicine.

It is a condition of the award that doctors should return home within twelve months of completing their fellowship work. One Nigerian doctor has already completed a year in Britain on a fellowship-Dr. A. E. Ifekwunigwe, who came to Britain from the General Hospital, Lagos, to study paediatrics. He returned home last June.

Last year one scholarship went to a Ghanaian surgeon.

DAGENITE
BATTERIES
give you a longer run for your money!



# London Course For Nigerian Immigration Officers

LONDON — Four Nigerian immigration officers are attending a special month's course in London which includes lectures on the latest immigration methods and visits to busy ports and airports.

The course, organised by Britain's Department of Technical Co-operation is being attended by fourteen immigration officers from Commonwealth countries. The Nigerians who have been granted fellowships to take the course under Nigeria/Britain technical assistance arrangements, are Mallam L. Sambo; from Zaria, and three immigration officers stationed in Lagos, Mr I. N. Gana, Mr E N. C. Okoye and Mr. A. O. Oredugba.

They arrived in London on January 17 and have attended lectures by immigration, procedure and general practice.

They have also studied immigration work on ships in the London Docks and at Dover and will also spend some time at London Airport.

---

## Ojowubinrin Pa Oko Re

( O bẹrẹ loju ewe kinni )

Gẹgẹbi irohin n a ti a gbọ lati ẹnu awọn ara Idumọta l'Eko ni adugbo awọn ologbe Onisemọ tiṣe ọkọ ojowubinrin na, a gbọ wipe obinrin yi ko si nile nigbati alejo omọge yi wa ba ọkọ rẹ ni enu ọna si wọ iyara lọ.

Gbati ti ojowubinrin ti de ti o gburo wipe ọkọ on moa obinrin mira lo ninu ile ni ara re ti bẹrẹsi gbona, o si ti agbara wọ inu yara tọ wọn lọ.

Ki ọkọ rẹ to fura, o ti yara ko ni woro abẹ mejeji, o ni "ṣe woro-abẹ ti o fi mba a lo na niyi"? o fun un si ṣin, ọkọ si bẹresi lọgun wipe ki awọn ara adugbo gba on.

Ki nwọn to de ọdọ wọn ninu iyara ọkọ ti ṣubu lulẹ *o* si ti ku bamubamu. Awọn ọlọpa wa lẹnu ibiti nwọn ti nṣe ọtẹlẹmu yẹ ọrọ na kiri lọwọ nisisiyi ṣugbọn ọwọ wọn titẹ obinrin na. Olodun are gba wa lọwọ awọn ojowubinrin.

## Awon Loya Tuntun

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Wali, Kano: Kalu Ifegwu, Ndi Ifegwu, Abiriba: Reuben Adeniyi Falusi, Akure: Adebayọ Osuolale Latinwo, Ibadan: Michael Enwelim Olunwa, Asaba: Sunday Akinola, Akintan, Idanre: Moses Akanbi Bọde Popoola, Abeokuta: Edmnnd Adegemi Adeboye, Abẹokuta: Michael Adeoye Adekoya, Ibadan: Louis Obiekw Aydaka, Onitsha: Michael Ifeanyi Akubeze, Onitsha: Umar Maidanma, Yaba: Samuel Adeleke Falade, Oshogbo: Francis Adekunle Owobisi, Lagos: ati Ezekiel Adeyẹmi Taiwo, Lagos.

Awọn ti nwọn yege ni MIDDLE TEMPLE ni: Oloye Cornelius Olaeye Taiwo, O. B E., Ibadan: Maxwell Fẹla Young, Lagos: Victor Oladipo Laleyẹ, Ọyọ: Boonamean Adenọla Ọladipọ Bakare, Lagos: Pius Egnabioje Esangbedo, Iguebẹn Ishan Divirion, Benin Province: Daniel Chukwukammadu Ohiri Njemanze, Owerri: Nathaniel Okereafor, Umuaga Nguru, Ngor, Owerri: Henry Adebọwale Odusanmi, Ijẹbu-Ode: George Odunfiyi Oduwọle, Ore-Awa: Matthias I. M. Ume-Ezeoke, Onitsha: Stephen Ejueyitsi Agbabi, Sapẹlẹ: ati Benjamin Oghewero Olokor, Ovrode Town, Isoko, Mid-West.

Awọn ti INNER TEMPLE ni: Ọgbẹni Simeon Ọlabode Eso, Ilesha: Ọlayiwọla Kusamọtu, Ikirun: Michael Olutayọ Adesanya, Ijẹbu-Ode: Samuel Ọmọtọṣọ Ajayi, Esaoko; Ilesha: Michael Adeleke Ọlayẹra, Ile-Ifẹ: Miss Ọbafemi Olufunkẹ Thomson, Ebute Mẹtta: Funsọ Adenuga, Ijẹbu: M. Salihu Moddibo Alfa Belgore, Ilọrin: Sadiku Ọmọkayọde Carew, Lagos: Samuel Ibukun Akinṣẹyẹ, Idanre: Felex Hosanna Eduvie, Benin City: William Andrew Owovukotu Tebite, Warri: Muritala Adebayọ Akande, Ibadan: James Bandele Alao, Imẹsi-Ile: John Ọlawale Aderinoye Babatunde, Abẹokuta: Adetunji Ọdẹbọ Ogunṣiji, Lagos: ati Sikirulai Ogunyọmi Alamu Ashimi, Lagos.



## Tani O Le Ranti Ojo Yi?

Aworan yi ni ọjọ ti Gomina agba Ọlọla DOKITA NNAMDI AZIKIWE gbayi to gbẹyẹ ni ọdọ awọn ara RẸMỌ ni Ishagamu. Ọba Akarigbo, Awolesi pẹlu Ọmọba Adeleke Adedoyin ni o duro pẹlu Ọlọla Gominaagba na lọjọ ti o lọ bẹ wọn wo ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 23, Kosọkọ Street, Lagos Phone 23370 Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467